## Kí ni àrùn mẹ́dọ̀wú onípele B (hepatitis B)?

**Àrùn Mẹ́dọ̀wú Onípele B jẹ́ kòkòrò tó ń gbé inú ẹ̀dọ̀ rẹ. Àràádọ́ta ọkẹ́ ènìyàn káàkiri àgbáyé ló ní àrùn náà.**

Ó ń tàn káàkiri lati inu ẹ̀jẹ̀ àti omi inú ara, bí àpẹẹrẹ lákòkóò ìbímọ. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ló ní kòkòrò náà nígbà tí wọ́n bí wọn tàbí nígbà tí wọ́n wà ní kékeré.

Níní àrùn yìí fún ìgbà pípẹ́ lè yọrí sí àrùn ẹ̀dọ̀ tó burú jáì (cirrhosis) tàbí àrùn jẹjẹrẹ ti ẹ̀dọ̀. Ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀ ènìyàn tó ní àrùn mẹ́dọ̀wú onípele B maa ń gbé ní ìlera.

Kò tí ì sí òògùn tó lè wòósàn. Àwọn èròjà ààbò ara rẹ tàbí ìtọjú ló lè kápá àrùn náà. Kíkapa rẹ lè dènà ìjàm̀bá búrubu.

Àwọn ènìyàn tó seése kí wọ́n ní àrùn mẹ́dọ̀wú onípele B lè gba àjẹsára ọ̀fẹ́ láti dáàbò bò wọ́n lọ́wọ́ rẹ̀.



**“Nígbà tí mo wà lọ́mọdé ni wọ́n kẹ́fín àrùn yìí lára mi, kò sì yé mi títí tí mo fi dàgbà.**

**Nísinsìnyí, mo ń dojúkọ àrùn naa nípa lílo àkókò pẹ̀lú àwọn ọmọ mi, rínrìn káàkiri lójoojúmọ́, àtí bíbá àwọn èèyàn tí mo fọkàn tán sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀.”**

## Ìsọ́fúnni àti àtìlẹyìn fún ọ

Kò burú láti ní ìbéèrè tàbí láti nílò àtìlẹ́yìn.

**British Liver Trust wà níbí fún ọ.**



Láti bá ẹnìkan tó mọ̀ nípa ẹ̀ sọ̀rọ̀, pe nọ́m̀bà ìrànlọ́wọ̀ tí àwọn nọ́ọ̀sì British Liver Trust **LỌ́FẸ̀Ẹ́** lórí **0800 652 7330**.

A ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àlàyé nípa àrùn mẹ́dọ̀wú onípele B. O tún lè darapọ̀ mọ́ Ẹgbẹ́ Àtìlẹ́yìn tàbí Agbègbè Orí Ayélujára wa.

Láti mọ̀ sí i ṣàyẹ̀wò kóòdù náà tàbí ṣe àbẹ̀wò sí britishlivertrust.org.uk/translate-hepb

A kọ ìwé pélébé yìí ní Oṣù Kọkanla, ọdun 2023.
Kóòdù: HBV/11/23.

British Liver Trust jẹ́ ilé-iṣẹ́ aláàánú tí a forúkọ rẹ̀ sílẹ̀ ní Ilẹ England àti Wales 298858, Scotland SC042140.

BRITISH LIVER TRUST

NHS

Yoruba Yoruba



# Wọ́n ṣèṣẹ̀ kẹ́fín àrùn mẹ́dọ̀wú onípele B ninu ara rẹ?

## Ohun tó yẹ kó o mọ̀

Wàá rí dókítà tàbí nọ́ọ̀sì akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ kan nípa àìsàn tó o ní.

O lè ní láti dúró fún ọ̀pọ̀ oṣù. Ó ṣe pàtàkì gan-an fún ọ láti lọ, kódà bí ara rẹ bá le.

Ìwé pélébé yìí wà láti ràn ọ́ lọ́wọ́ nígbà tí o bá ń dúró. Ó sọ fún ọ nípa:

- Ohun ti àrùn mẹ́dọ̀wú onípele B jẹ́
- Ohun tí yo ṣẹlẹ̀ léyìn náà
- Dídáàbò bo àwọn ènìyàn mìíràn
- Mímójú to ìléra rẹ
- Ibi tí o ti lè rí àlàyé àti àtìlẹyìn sí i

## Ohun tí yo ṣẹlẹ̀ lẹ́yìn náà

O ní láti lọ rí akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ kan nílé ìwòsàn. O lè ní láti dúró fún ọ̀pọ̀ osù. Gbìyànjú láti má káyà sókè. Ṣe àkọsílẹ̀ àwọn ìbéèrè tó o máa mú dání. O lè béèrè fún ònġbúfọ̀ tí o bá nílò rẹ̀.

Akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ dókítà náà yóò ṣe àwọn àyẹ̀wò bíi àyẹ̀wò ẹ̀jẹ̀ àti àyẹ̀wò ẹ̀dọ̀ láti mọ:

- Bí kòkòrò náà ṣe lágbára tó
- Bóyá ẹ̀dọ̀ rẹ ti bàjẹ́
- Bóyá o nílò ìtọ́jú

Mímú kí agbára àrùn náà lọ sílẹ̀ kò ní jẹ́ kó ba ẹ̀dọ̀ rẹ jẹ́. Lọ́pọ̀ ìgbà, ètò ààbò ara rẹ lè ṣe èyí. Àwọn èèyàn kan nílò ìtọ́jú, èyí tó sábà máa ń jẹ́ oògùn oníkóró tí wàá máa lò lójoojúmọ́.

Ó ṣe pàtàkì gan-an láti lọ sí gbogbo ìpàdé àti àyẹ̀wò rẹ. Kódà bí ara rẹ bá le tàbí tí o kò bá gba ìtọ́jú. Kòkòrò náà lè túbọ̀ lágbára síi, kó sì ti ipa bẹ́ẹ̀ ba ẹ̀dọ̀ rẹ jẹ́ láìmọ̀.

**Àbájáde àyẹ̀wò rẹ jẹ́ àṣírí. Wọn kò ní ipa kankan lórí ànfààní láti bèèrè fún ààbò tàbí láti yanjú ẹ̀sùn àtìpó.**

## Dídáàbò bo àwọn ènìyàn mìíràn

Àwọn èèyàn tó sún mọ́ ọ náà lè ní àrùn mẹ́dọ̀wú onípele B. Tàbí kí wọ́n ti ni gan. Lára wọn ni:

- Àwọn tó ń gbé nínú ilé rẹ, títí kan àwọn ọmọdé
- Àwọn èèyàn tí ò ń bá ní àjọsepọ̀

O lè ràn wọ́n lọ́wọ́ nípa bíbá wọn sọ̀rọ̀ nípa àbájáde àyẹ̀wò rẹ. O lè fi ìwé pélébé yìí hàn wọ́n láti ṣàlàyé.

Àwọn èèyàn tó sún mọ́ ọ ní láti béèrè fún **àyẹ̀wò ọ̀fẹ̀ fún àrùn mẹ́dọ̀wú onípele B** ní ilé-ìwòsàn wọn láti mọ̀ bóyá wọn kò ní àrùn náà. Wọ́n tún lè rí **àjẹsára ọ̀fẹ aílèléwu** tó ń dáàbò boni lọ́wọ́ àrùn mẹ́dọ̀wú onípele B gbà.

Ọ̀fẹ́ ni lati forúkọsílẹ̀ pẹ̀lú GP.
Ṣe àbẹ̀wò sí www.nhs.uk/service-search/find-a-gp láti wá èyí tó sún mọ́ ọ.

Àwọn èèyàn máa ń kó àrùn Mẹ́dọ̀wú Onípele B nígbà tí ẹ̀jẹ̀ tàbí omi ara bá dà pọ̀. Èyí túmọ̀ sí pé èèyàn ò lè kó o àrùn náà nípa ṣíṣe tàbí pínpín oúnjẹ, dídì mọ ara ẹni tàbí fífẹnu ko ara eni lẹ́nu.

O lè dènà kí kòkòrò náà má tàn dé ọ̀dọ̀ àwọn ẹlòmíràn.

- Lo ọ̀rá ìdábòòbò kọndọọmu tàbí dáàmù láti ní ìbálòpọ̀, àyàfi tí ẹni keji rẹ bá ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára tàbí tí òun náà bá ní àrùn mẹ́dọ̀wú onípele B.
- Má ṣe pín ohunkóhun tí ó lè gba ẹ̀jẹ̀ dúró fún àpẹẹrẹ abẹfẹ́lẹ́, búrọ́ọ̀sì ìfọyín, abẹ́rẹ́.
- Bo àwọn egbò, awọn ojú ibi tí o yún àti àwọn ọgbẹ́ pẹ̀lú pilasita kí o sì fọ ẹ̀jẹ̀ tó bá kán sílẹ̀ pẹ̀lú omi ìṣídọ̀tí.

## Mímójú to ìléra rẹ

O lè ṣe àwọn nǹkan kan láti bójú tó ìlera rẹ nísinsìnyí, nígbà tó o sì ń dúró de ìgbà tí wọ́n máa pè ọ́.

- Máa jẹ oúnjẹ tó ń ṣara lóore
- Má ṣe mu ọtí
- Máa ṣe eré ìmárale
- Máa sùn dáadáa
- Lọ fún gbogbo àyẹ̀wò rẹ
- Máa sọ fún àwọn òṣìṣẹ́ ìlera pé o ni àrùn mẹ́dọ̀wú onípele B, kí wọ́n lè mọ̀ bóyá o lè lo oògùn láìléwu.

Mójú to ìlera ọpọlọ rẹ náà. Bíbá àwọn èèyàn sọ̀rọ̀ lè ṣèrànwọ́. Ronú nípa ẹni tó o lè fọkàn tán, kó o sì bẹ̀rẹ̀ níbẹ̀. Ẹgbẹ́ British Liver Trust ní àwọn Ẹgbẹ́ Àtìlẹ́yìn níbi tóo ti lè pàdé àwọn èèyàn mìíràn tí wọ́n ní àrùn mẹ́dọ̀wú onípele B.

Àrùn Mẹ́dọ̀wú Onípele B kì í sábà ní àmì àìsàn kankan. O lè ní ìmọ̀lára bí ẹni pé o ní àrùn gágá tàbí kí ara máa yún ọ. Fún ìrànlọ́wọ́ láti ṣàkóso àwọn àmì yìí, bá oníṣègùn GP rẹ tàbí ilé ìtajà oògun rẹ sọ̀rọ̀.

**Àrùn Mẹ́dọ̀wú Onípele B lè fa ìṣòro ńlá. Bí o bá ní èyíkéyìí nínú àwọn àmì wọ̀nyí lọ sí A&E:**

- Níní ìmọ̀lára pé ó rẹ ni gan
- Awọ̀ tàbí ojú pípọ́n (ibà pọ́njú-pọ́ntọ)
- Ikùn tó wú
- Pípọ ẹ̀jẹ̀ tàbí yíya ìgbẹ́ tó dúdú tó dà bí ọ̀dà dúdú

Pe nọ́mbà ìrànlọ̀wọ̀ tí àwọn nọ́ọ̀sì **British Liver Trust LỌ́FẸ̀Ẹ́** lórí **0800 652 7330.**